# IWADI IJINLE AGBAYE NIPA EJE TI NSOFO LEHIN IFARAPA

## Iwe Ilaniloye ati ifowosi fun awon alaisan, awon ebi, ati asoju won

Ti o ba ni ibeere nipa kikopa ninu iwadi agbaye yi nipa eje ti nsofo lehin ifarapa, jowo kowe si adiresi yi:

(FI ORUKO ATI ADIRESI ILE IWOSAN SIHIN)


IBUDO ISE-AKOSO IWADI:
International Study of Bleeding After Injury, Room 180
London School of Hygiene & Tropical Medicine
Keppel Street
London WC1E 7HT
United Kingdom

Tel +44 20 7299 4684
WWW.CRASH2.LSHTM.AC.UK



ISRCTN86750102
Version 3: 07/02/05

**Ile iwosan yi nkopa ninu iwadi ijinle lati wa ona lati dekun eje yanturu lehin ifarapa yanna-yanna.**

**(1) Ati yan o lati kopa ninu iwadi yi**

**(2) A fe fi o sinu awon ti yio kopa ninu iwadi yi**

**(3) A fe fi ________________ (oruko alaisan) sinu iwadi yi.** *(jowo yi odo yika okan ninu awon isori wonyi)*

## OHUN TI O YE KI O MO NIPA IWADI IJINLE:

Iwe pelebe yi wa fun itosona fun o nipa iwadi ijinle, ni Pataki julo nipa awon idi iwadi, awon ewu ti o wa nibe ati awon anfaani ti o wa ninu kikopa ninu iwadi na.

Ninu ile iwosan yi, awon alaisan to fi eje sofo pupo ma ngba itoju pajawiri ti a nfun gbogbo eniyan to seje pupo. Ero-ngba iwadi ijinle yi ni lati wa itoju ti o dara ju ti atehin wa lo. A lero wipe itoju titun nipa iwadi yi yio ran eje didi lowo, ti yio si jeki eje ti alaisan yio padanu dinku, nipa eyi yio din eje ti eni ti o farapa yio nilo ku. Sugbon sa, itoju titun yi le sokunfa eje didi nibi ti ko ye tabi wulo. A ni ireti wipe a o le so pato ati lati fi idi re mule pe anfaani itoju titun yi yio po ju ipalara ti o le se lo, sugbon eyi ko ti ni idaniloju. Jowo ka ohun ti a ko si isale daradara ki o si bi onisegun dokita re ni ibeere ti o ba ni.

### 1) *Kini idi ti a fin se iwadi ijinle yi?*

Siseje yanturu je ohun ti o wopo ninu awon nkan ti nsokunfa iku lehin ifarapa, nitorina, o se Pataki lati wa ona ti o dara ju ti atehinwa lati din eje ti awon eniyan npadanu ku.



### 2) *Nitori kini a se nse iwadi yi?*

A nlo oogun Tranexamic acid ni opolopo igba lati dekun di eje to nsofo ku lehin ise-abe nla gege bi ise-abe okan. A nse iwadi yi lati mo boya oogun yi tunle dekun siseje lehin ifarapa nla. Oogun Tranexamic acid kii se egbogi titun, o si je ona itoju ti gbogbo eniyan fowosi fun itoju aisan ti o ba la fifi eje sofo lo.

### 3) *Tani o nse iwadi yi?*

Dokita __________________________ ni o nse akoso iwadi yi ni ile iwosan yi. A nsakoso gbogbo agbaye iwadi yi lati odo awon onisegun ti o wa ni ile eko ijinle unifasiti ni ilu oke okun London.

### 4) *Alaisan ko le kopa ninu iwadi yi bi o ba je wipe:*

- Alaisan ko ti to omo odun merindinlogun
- Alaisan ti o ba ni ipalara ju wakati mejo lo ki o to de ile- iwosan
- Ti onisegun bar o wipe idi kan pato wa ti ko fi ye ki a fun un ni egbogi tranexamic acid
- Ti onisegun ba ro wipe idi kan pato wa ti o fi ye ki a fun un ni egbogi tranexamic acid

### 5) *Kini o ti sele* / **kini yio sele ninu iwadi yi?**

A o fun o (tabi alaisan) ni gbogbo itoju pajawiri fun eniti nda eje,pelu fifa omi si ara re (tabi alaisan) fun eje ti o ti padanu. A o fun o (tabi alaisan) ni idinwon egbogi tranexamic acid ajo-oogun-mase kan ti a npe ni omi-iyo. A o fun o ni idiwon eyikeyi ninu meji yi fun wakati mejo gbako.

Yiyan eyiti a o fun o ninu mejeji (oogun gidi tabi ajo-oogun mase) ni a o ti se pelu ero ayarabiasa ni ilu oxford in oke okun. Onisegun ti o nboju to o /tabi se itoju alaisan ko mo boya oogun gidi ni o gba ni tabi ajo-oogun mase. Imo nipe eyi ni a o pamo nib o-nkele ni ile-iwosan miran. Iwadi yi ko la ayewo miran lo sugbon onisegun re yio se akosile finifini nipa bi o se wa eyiti yio fi ranse si ibudo akoso iwadi ni ilu London. Akosile yi ni awon ti nsise lori iwadi yi yio lo nib o-nkele ti won ko si ni tu asiri re funenikeni bi o ti wu ki o ri.

## 6) *Awon ewu wo ni o wa ninu kikopa ninu iwadi yi?*

Tranexamic acid je oogun ti o gbajumo ni lilo ati wipe titi di asiko yi ko ti si arigbamu kan pe oogun yi npanilara niwon igbati a ba lo o fun igba kukuru. Oogun yi Tranexamic acid kii se oogun titun rara.

## 7) *Awon anfani wo ni o wa ninu kikopa ninu iwadi yi?*

A lero wipe oogun tranexamic acid yi yio se iranwo lati din eje pipadanu ku. Imo ti a ba jogun ninu iwadi yi yio ran opolopo eniyan ti o ba fi ara gbogbe lowo ni ojo iwaju.

## 8) *Ti o ba ni ibeere tabi isoro, tani o le kesi?*

Ti o ba ni ibere o le kesi

Dr ________________________________________

Pelu ero telifonu ______________________________



## 9) *Awon imo wo a ma fi pamo?*

Gbogbo ohun ti a mo nipa re /tabi alaisan ati ogbe re /tabi ogbe alaisan ni o se ni moonu tabi bo-nkele. Awon eniyan kan soso ti o ni anfani ati wo akosile ni awon onisegun ti o se iwadi yi, awon osise ibudo-isakoso iwadi ati awon alase ti o nse amojuto lati rii wipe iwadi naa nlo gege bi o se to labe ofin. A o gbe abayori iwadi jade ninu iwe imo nipa isegun kan ki awon onisegun le je anfani imo na, sugbon sa, a ko ni ko ohunkohun nipa enikeni beni ko si le si ona ati da enikeni mo.

## 10) *Nje iwadi le tete pari fun alaisan bi?*

Oogun itoju iwadi ni a fun ni gege bi ti itoju pajawiri. A lero wipe e o je ki a lo imo nipa bawo ni o se se pelu iwadi yi/tabi bi alaisan se se pelu iwadi, sugbon bi o ko ba fe ki a lo imo naa, jeki onisegun re mo.

## 11) *Nkan wo ni o tun ye ki o mo?*

- Awon ti o pese owo lati se iwadi yi ni unifasiti ti ilu London ati ajo ti nmojuto iwosan agbaye,kii se ile ise ti o se egbogi tranexamic acid.
- Ile eko ijinle London School of Hygiene & Tropical Medicine gege bi ibudo isakoso iwadi yi gba ojuse re lati s’atilehin gbogbo inawo ti o ba suyo ninu iwadi yi. O si setan lati sanwo itanran fun enikeni ti o ba se ijamba kankan nipa kikopa ninu iwadi yi, ti kii ba ti se afowofa.

# IWADI AGBAYE NIPA SISEJE LEHIN IFARAPA

# IWE IFOWOSI
(ti o ba nilo)

**O yemi yeke ohun ti iwadi yi wa fun inu mi si dun**

1) Lati kopa ninu re
2) Lati je ki a lo akosile lekunrere nipa imularada mi fun iwadi yi

**TABI, ti o ki ba se alaisan**

3) Ki awon eniyan ti a daruko nisale yi kopa
4) Pe ki a lo akosile lekunrere nipa imularada awon alaisan naa ninu iwadi yi

Amin oruko re: ______________________________________

Ojo oni: ______________________________________

Oruko alaisan:______________________________

Oruko onisegun ti nbere fun ifowosi:

______________________________________

Oruko eniti o se ifowosi:

______________________________________

Ti o ki ba se alaisan, bawo ni o se ba a tan?

______________________________________

YORUBA

ISRCTN86750102
Version 3 : 07/02/05